Owe
KITA- ... KO O ... ARISIKI KI A' SISE ... ERU K DA NKAN.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

Asoje
E... ma ... ...enia ... t'en ... ... wen ko n'gbo A ... omode ko le ka ... Oje yi ... ma doyiba ni.

VOL. XIII No 806 LAGOS SATURDAY NOVEMBER 25, — DECEMBER 1st, 1961. KOBO MEJI (2D)

# OBINRIN ABILEKO KAN BA AJA JA, O SI BU AJA NA LORUN JE.

Ọmobinrin abilekọ kan nilu Djakarta ni iha Iwọ-orun ilẹ Java, bu aja kan jẹ lọrun, o si ja o un ọna ọfun aja na, Beria ni orukọ ti aja na nje, lẹsẹkẹsẹ ni o si ku.

Ẹniti o ni aja na sọ wipe on yọwọ-yọsẹ kuro ni-lu yi nitoripe on ti takiyesi wipe ... ọrun kogb'ẹbọ si Beria, Aja on ati obinrin na.

Eyi ...,  aja ko tun mbu enia jẹ mọ, enia l'o tun mbu aja jẹ. O ṣe kel bọ !

## Dokita Chike Obi Jagun Molu

DOKITA Chike Obi ti a nwo ni ọwọ ọtun ... aworan yi ni ẹniti o jagun molu ninu idibo Ila-Orun ti nwon ṣe lẹsẹ tokọja.

Ki a maṣe gbagbe wipe Dokita Chike Obi yi



ni ẹniti o kuro ninu Ile Igbimọ Apapọ ... ala tilu Eko, o si bọsi Ile Igbimọ Ila-orun.

## Oba Obinrin Fi Ilu Ghana Sile


DOKITA NKRUMAH

TAKORADI-Ni ọjọ Atalata, ọjọ kọkan'e-logun oṣu yi ni Alakoso ijọba ilẹ Ghana sin ọba obinrin wọkọ oju-omi lọhun abewo rẹ lọ si ilu Liberia.

Ki ọba to wọkọ, o ṣe apọnle ilẹ Ghana bi o ti le agba ni ilẹ Afrika ninu ẹmọ ẹgbẹ awọn ilu ti mba Gesi sepọ 'Commonwealth' o ni iranran iyebiye ti o le mu ilọsiwaju ba ẹgbẹ na.

(Wo yoku loju ewe kefa)

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1933.
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
88/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Nathazigr London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURGH

# Omi Doba Nile Ketu

IBADAN - Al Lojuto ise Ijọba ipinlẹ Iwọ orun ti fi ase si efir kilọ omi ilo kilo nilu Ibadan ni ojọ Monday wipe enikẹni ko gbọdọ fi omi ẹrọ fọ mọto tabi oko ilẹ, yalu moto aketu tabi ayọkọle ti fanji titi ti ... yio fi se olln miran nigbati omi ba rọju nilu

Emikeni ko gbodọ fi omi ẹrọ fọ asọ tabi ki o ma fi fo awon ohun elo miran yato si ohun elo ile. beni ako gbodo fou si itanna, eweko, ninu ọgba tabi ki a fi ma dẹ ile oko.

Nje, Owelawon agba ti o sọ wipe "Omi d'ọba nile Ketu ti a fi se akọle irohin ... baje otito bi ?

# ELETI-OFEDARABA

Advt. 211

## Federal Ministry Of Finance

GOVERNMENT OF NIGERIA 3 1/4 o/o REGISTERED STOCK

The above will be redeemed on 1st December, 1961. A circular Notice has already been sent to all Stockholders at their last-known addresses, incorporating a form of claim for payment.

Any stockholder who has not received such a notice should immediately write to this office, with the request for a form of claim for payment.

(Sgd.) R. E. MARSH,
Accountant-General of the Federation,
for Permanent Secretary,
Federal Ministry of Finance.

Mosaic House,
Tinubu Square,
Lagos.

1st November, 1961.

# Ekun'mi nja nibi gbogbo

KADUNA - Laiye yi ni a gbo irohin ẹkun-omi tabi omi ti o ya wolu, nilẹ India, eyiti a tun ri gbo pe o ran opolopo enia sorun o si so ogunlogo enia di alaini ile lori.

Wo yoku loju ewe keran

# AWAMOTO TI KOBIKITA TI NWON NSA EREKERE E LO SORA




**Aworan ti a nwo yi nfi ise buburu ti awamo. ti ko bikita nse larin ilu fun ikilo ti nwon se si oju opopo ona.**

**Enyin Awamoto, eso d'owo yin o**

## Kogbona Ko Tutu Ni Ilu Kongo

ELIZABETHVILLE - Ni ojọ Monday ni irohin ija ti ibid awon Baluba gbe fi ara pamọ si tun kan wipe enia ti o ku je mokandinlogbon

Nwon tun ri oku enia bi mejidinlogun nigbati nwọn nto ibugbe won wo ni ojo Wednesday.

# OWEILEYORUBA

**Abat taa ketebi eni tikoba odotan.**

# ITAN OKO ATI IYAWO RE

NI ọjọ kan B.la yi jẹ agbin hauhu osi ni Iyawo kan Iyawo rẹ si b'ọmọ ka fi mọ na si je arẹwa ọmọ lehin ọ mọ yi awọn mejeji ko bi ọmọ miran rara titi ti mama ọmọ yi fi ku nigbati Iya ọmọ na ku Iya si bẹrẹ si je ọmọ na pupọ

Baba ọmọ na si lọ fe obinrin kan, o fi ṣe Iyawo tabi lati ma se itoju ọmọ yi ti on ko bi si ni ile Oruko obinrin na nje m l wa B br yi ko s mọ wipe obinrin ije ni (n fe ... si ile

Ni ọjọ k n obinrin yi si ta ... omo na si ku ki baba re to de lati oko r bi ọmọ ra ti ku si gbe lo s n, Nigbati Baba omo yi de o si bere pe ... ni Jimo lo ? obinrin yi ... si dahun pe nigbati o ba on ja ni on ba sa ... osi ku o... ti s n B ba omo yi s ... koturu.

Ni gba ti omo y ku tan ti o ba di oru asi ko aw n egbe re l si oko baba re gbogbo won yi bere si igbo ṣa Ngb ti baba yi ba de oko yio ma so wipe, ou k ma sa oko de ibiyi ni ana bena ni ọjọ keji ati ọjọ ke a bayi ni baba ba lo si ile Babalawo lat lo ye wo Babalawo si so f un pe omo re ti o ti ku ni won ba o nsa oko re ni oru osi so fun babalawo pe bawo ni on se le ri mu w a si ile.

( Wo yoku loju ewe karun )

# OKU'JA WOLU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ENITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO, NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI ỌGUN TI ONIṢOWO LE SE TI ỌJA RE YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA

## E Polowo Oja Nyin Sinu

## IWE IROHIN ELETI-OFE

# ELETI-OFE D'ARABA KOSEGBE

## Awon Apon'mita



Aworan awọn apọn omi ta ti a nwo yi konl wipe ko yẹ ki a ma lo emi sofo, nitoripe ni ilu miran nile wa Nigeria yi, ọpọ jajin rere ... awọn enia ti riṣe pupọ emi fun mimu ati lilo.

# Imọran Fun Gbogbo Omo Ile IGbomina

Lati owo Orilonise

Olotu,

Jọwo gba i laye lati na awon enia mi soro isin ati ọgbon akoko m ju ba lo ọeyin alagba, lokunrin ati lobinrin ati Ẹyin odomokunrin wa. Nitori bi Ekolo ba tijuba ile, ile gb o lanu fun u, ki ibami sọ.

Ẹjowo oro mi na kepo tobẹ jube lo, Owe awon baba wa kan sọ bayi wipe Korowo-topa-Ọmọ ẹsin O nbẹ wa pa ọmo enia. On wipe iru iwa ati fitina ti Ọba Ilọrin nfun Ilẹ Igbomina mefe ki a mo daju wipe Olu wa ṣiwaju wa. O si kẹhin wa nitori inu kan, ọkan kan lafi so wipe - ki Oluwa fi ọwọ ara rẹ fun wa ni "Division" Oluwa Olodumare yio si ṣe bee fun wa. Amin Aṣẹ.

Gẹgẹbi iru awọn aidara ti ọba Ilori nṣe fun wa ni ilẹ Igbomina iwa na lofi han Ojiṣẹ Olorun kan ti oruko re am je Iburaimoh Kech nitori wipe o ti wa han si gbogbo omo ile Igbomina mope yi tedun-tedun ati okan ile lokunrin ati lobinrin lomode ati lagbalagba ti o jẹ omo Ẹgbẹ Igbomina parapo Action Group Alliance ta omo ẹgbẹ Northern Peoples Congress ẹ jeki a ronu wo wipe akoko ti awi.

Wo yoku loju ewe karun

## Itan Ijapa Ati Abuke-Oba

Ni ęjo kan, Igbin dę takute si oke rę, ękunrin ka wa ti oruko rę eje Abuke-oba. O di ęjo kan Ijapa wa ęgbon ti o le fi pa abuke oba, Igbati ijapa mo pe igbin de takute si oko re o tan Abuke-oba hi o ba on lo si oko on. Igbati won de ohun, Ijapa pa Abuke-oba, o lo gbe si ibi taku Igbin, bi o ti gbe si bę tan, ni o sare lo sile, to lo so fun oba Nigbati o de odo oba oyi sotu, oyi sosi o ni ki oba pe. Oni on ri oku-oba ni oko igbin.

Bi oba ti gbo, o ranse re igbin, bi igbin ti de oba pase pe ki nwon dse. Igbin nbę oba o ni ki o o gbo ti enu on ki won to de on.

Oba pase pe ki won tu Igbin so fun oba pe ki oba fori ji on pe ki se on lo pa Abuke oba. Oba ko gba gbogbo alaye ti igbin se. Igbin tun bę oba ki o fun on ni ęsin ati aso to dara, Oba pase pe ki nwon se igbin leso.

Bi igbin ti wo aso to dara, ti o si gun ęsin ni eto pe jo 'e koriti awon si ako orin wipe "igbin pa abuke oba, oba da igbin lola igbin gun ęsin roboto" bi gbogbo enia ti nko orin lo ni Ijapa jade lati ino ile re wa ti o nwo igbin bi won ti se loso, ara ta Ijapa titi o fi lo si ile oba wipe on lo on pa Abuke oba, oba bere bo ti pa, Ijapa se alaye, oba ba pe awon ęmęwa re pe ki won gbo nkan ti Ijapa wa so.

Igbati Ijapa se alaye tan, oba pase pe ki nwon mu ida ti awon fi pa ijapa fun ise to e. Bayi ni Ijapa di eni egbe. Oba da igbin sile ki o ma lo ni alafia Oba si da ile-re ati ona re si meji. oko kan fun igbin.

Bayi ni ijapa fi oju kokoro pa ara rę. Itan yi kowa wipe ki a mase se oju kokoro.

---

LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

E Maa Ka
Iwe Irohin
Eleti - Ofe
Losose

## NWON PADE NIBI APEJE NILU OYINBO



Igbakeji Asoju ilę Nigeria nilu Oyinbo, Dokita Omolo'u ati Ogbeni M. M Ahmed, ri nwon jumo ejewo po nibi apeje fun awon omo akeko olofe ti Igb'mo Majoba'e Agbaiye nilu Oyinbo.

## Bere-bere koni Sina

Inu mi yio dun pupo bi Olotu ba le gba mi laye lati fi ibere mi kekere wonyi siwaju awon agba ati awon omowe ilę Yoruba fun alaye.

1. Enitio bi omo ti o nta eyiti o bi omo ti o npaje ati eyiti o bi omo ti o fi nsan gbese ainidi. Ejowo, ewo l'o san ninu awon metęta.

Emi ni S. K. Moyo.

# ITAN OKO ATI IYAWO RE

(Lati ọwọ F. O. Lasisi)

BABALAWO si ti seni ki o si oko ni ale ọjọ kan ki erọra lọ fi ara pa mọ si abẹ igi ni ibiti gbogbo wọn yio so kale si, wọn asi ko Iyẹ wọ silẹ ni ibẹ iyẹ t i rẹ n i funfun ti awọn Iyoku re ni dudu ki o si mu funfun yẹn wa si ile yio si ba yin wa si ile ni ọjọ keji Baba yi si ṣe be bi awọn ọmọ yin ti sọ kalẹ, gbogbo wọn si ko gbogbo Iyẹ wọn sile wọn si bẹrẹ si o igbo n ṣisa o si rọra lọ mu iye na o pada sile.

Nigbati awọn ọmọ yi de lati pada si ajule ọrun gbogbo wọn si ko iye na owa ku ti ọmọ yi nikan ni o ba bere si sun'kun o sun titi ko ri Iyẹ re gbogbo awọn ti o ku si ti pada si ajule ọrun ti wọn ko ba si mu iyẹ yi lọwọ wọn ko gbọdọ wọ ajule orun.

Baba yi si fi ibi ti Iya na gbe wa han Iyaworẹ nigbati Baba yi de oko o si ri ọmọ yi ni ibi ti oti nsunkun osi gbe lọ si ile ọmo yi si ka gbogbo ewọ on fun Baba re yi o si ni on yio mu ṣe ni ọmọ yi bade ile.

Ni ọjọ kan ni Baba yi lọ si oko re osi lọ sa oko ni Iyawo baba yi ba lọ pọn omi o si da si inu amu ya osi tun lọ la igi o si fi arike sa Igi na ni ọmọ yi ba gbo o si ti sọ fun baba re pe wọn ko gbodọ fi arike sa Igi wọn ko gbọdọ da omi si amu ko ṣe yan, wọn ko si gbọdọ ja ọmọ yi si bẹrẹ si sọ kun o si so fun ọmọ yi pe kini ṣe o ọmọ yi si sọ fun pe se bi Iwọ ni oda omi si iny amu yaa o si tun fi arike ṣa igi ọmọ yi sa tẹrẹ si so kun titi ti baba rẹ fi de.

Nigbati Baba rẹ de o si be darajara o si pa eran fun ni gba ti odi ẹjọ keji Baba yi si gba ọna tirẹ lọ Bayi ni Iyawo Baba yi nse fun ọmọ yi ni ọmọ yi si bẹrẹ si sun kun nigbati obinrin yi ma dahun o ni kini ṣe ọ o si sọ fun ọmọ yi pe iye re lo wa ni oke yẹn ọmọ yi si gun oke osi mu Iya re osi lu ẹsẹ mọle bayi ni ọmọ yi se lo si ajule ọrun.

Nigbati Baba de o si bere ọmọ rẹ ni obinrin dahun pe oti mu Iya rẹ o si ti lu ẹsẹ mọlẹ emi ko si ri mọ. Bayi ni obinrin yi ti sọ fun ọkọ rẹ ọkọ re si ba obinrin yi ja dada baba yi si pa obinrin na.

Itan na ko wa wipe ki ama ṣe ko irira ọmọ nikeji wa.

Ẹ o Ma Gburo mi L'ọsẹ ọsẹ

## Imoran Fun Ọmo Ile Igbomina

(O bere loju ewe kẹta)

na tito. Ẹfufu si ti fẹ, o sa ri rugbin ... ni Ọsẹ nru gbede gbede, ṣugbọn Oluwa le mo ... yi ... Yala Ẹ ... tabi omọ.

Isade okunkun Parada. O tito asiko fun a lati bere ... babawa nile Igbomina, Ẹ jowo Ẹnyin ọmọ Ẹgbẹ N.P.C. Olọni ilẹ Igbomina, ejowo mo bẹ yin gidi gidi, e ma ṣe jẹki alo ... inu, mo fi nhan yin wipe Ọba Ilorin ko si fun ọmo ilẹ Igbomina. Lati tunṣe biko ṣe lati baje, emi yio sun siwaju die gegebi ohun ti atigbọ.

Ẹyin ọmo Ẹgbe N.P.C mofe ki ... Owe awon Baba wa kan to so bayi wipe, "Ẹhinkule lota wa, ile ni aṣeni ngbe", toto Oṣe bi owe. On nipe, arika ninu iwe irohin wipe won mu okan' ninu awon Olori A.G. ile Igbomina, Oruko Ọlọla wa na ama je Mr J.T. Obaoye, (the A.G. (Organisin Secretary) o si jẹ ekan ninu Ekiti parapọ ti wọn si de awon obinrin won si lati malu.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

## Ekunmi Nja Nibi Gbogbo

(O bere loju ewe keji)

Eyiti a tun ri gbọ niti omi odo Gamboru ti o ya wọlu ni egbegbe Dikwa ti Sardsuna. A gbo je opolopo ile ni omi na ti bi le ni omi na ti baje nilu Gamboru, Ijoba Ariwa si ti ran osise ti o ni imo nipa re lọ ki awon le tete kapa omi na ki o to gbile siwaju.

Nwon koiti le so iye owo ohun ini ti omi na ti baje.

Ki Oluwa ṣọwa lọwọ ija omi.

## E Ma Se Fi Omi Sofo




**E kilo fun awon omo nyin ki nwon mase lo o m i n i ilokulo**

## Awon Idile Ajanaku, Araba Eko Se Odun Ifa

Ni ọjọ Aiku ti nṣe ọjọ 12th oṣu yi, ni awọn idile Oloye Ajanaku Araba Eko ṣe ọdun Ifa ni Agbole Ajanaku, 55, Olepẹṛo Street, Eko.

Ikunlẹ ọdun na lere, ni dede agogo mẹkanla alẹ ni alẹ ọjọ Abamẹta (Saturday) ti nṣe ọjọ kọkanla oṣu yi (Nov. 11), ni Iga Ifa Ajanaku.

Olukulaku li ọkunrin, li obinrin li wọn pesẹ si ibẹ ti awọn si ntọrọ ire li ọdọ (Olodumare), ti wọn si tun nsun Iyẹrẹ Ifa (eyi ni wipe bi wọn ti tọrọ ire li ọdọ Olodumare ni wọn fi ohun ijinle Ifa kọrin iyin si Olodumare). Bayi ni wọn ṣe titi di agogo marun owurọ ọjọ Aiku (Sunday). Awọn ti wọn si nṣe iwure na fun wọn ni Oloye Fagbemi Ajanaku, Araba Eko, ati Oloye Ṣọ'akunmi Ajanaku, Apena Oshodi.

Ni Idaji yi ni olukuluku lobinrin, ni iyawo ile ati li ọmọ ile lo mura, ti ẹniti o ro aṣọ oke sanyan nro sanyan, ẹniti o ro lace ro lace, ẹniti o ro o ro aran ogbogbo lọ suwa. Gbogbo wọn funfun bi Lekeleke, olukuluku wọn si gbe 'Igba Ire' ti a tun npe ni Igba Iwa ru, ti wọn si to ni ọkanokan ti wọn njo Ipese Ifa Olori Ebi Iya Afin Fakolade Ajanaku ni aṣiwaju awon ọmọ ile lobinrin, agba-Apẹtẹbi Orunmila ni o si siwaju awon apẹtẹbi (Iyawo).

(Iyoku di ọsẹ ti o mbọ)

## Imoran Fun Omo Ile Igbomina

(O bere lo ju ewe keren)

Lalai ko jẹbi ọrọ na jẹ iyalẹnu fun wa. Ejọwọ mefẹ bi gbogbo ẹyin ọmọ Ibilẹ Igbomina lere wipe njo eyi dara ?.

Nitori kili ile Igbomina le dara fun gbogbo wa n teri di eyi mebẹ yin lẹ ọkọ ọmọ mefẹ ki e ranti wipe ọla ọmọ bibi eni gbogbo wa lo wa ni ile Igbomina bi awọn Baba wa ti bi wa loni awa na sin ti awọn, e mase jẹki Agba ile Baba wa ta fun awọn Fulani e jẹ wọ e ṣọrọ wipe mo ntun npada sẹhin Mo mọdaju wipe "Ilọrin" koko wa lẹ ruri ki isi ṣe wipe Ilorin ni ati jade wa.

(Iyoku di ọse to mbọ)


OPO TYRE MOTO

TERCO

Ni

-x- TAYA MOTO TI A SỌ DI TITUN

-x- TI OWO RẸ ROJU

-x- TI OJA RẸ TA

-x- TI O SI NI AGBARA PUPỌ

Wa Fun Tita Ni Ṣọbu Wọnyi:-

NIGER MOTORS

ODUNLAMI STREET, LAGOS.

JOE ALLEN

TINUBU STREET, LAGOS.

Faramobi Stores

NO. 60, KOSOKỌ STREET, 98 TOKUNBỌ ST. ati NO. 31, GREAT BRIDGE ST, LAGOS NIGERIA

On ni awọn Onibara ti o gbọn ura.

VERY SPECIAL XMAS BARGAINS !

ALL St. Michael LADIES COTTON DRESSES FROM 63/- to 39/11d.

ALL St. Michael MEN'S TERYLENE TROUSERS
LIGHTWEIGHT from 84/- to 69/11
HEAVYWEIGHT from 95/- to 79/11

ALL St. Michael MEN'S SHIRTS

20 o/o OFF FIXED PRICES

THIS OFFER COMMENCES TODAY 25TH NOVEMBER AND CLOSES ON THE 24TH DECEMBER !

MANY OTHER BARGAINS TOO !

LEVENTIS

DEPARTMENT STORES

MARINA & MAINLAND


## Oba Obinrin Fi Ile Ghana Sile

(O bere loju ewe kini)

O tun so ninu ọrọ rẹ wipe abewo ti on pẹlu ọkọ on wa bẹ ile Ghana wo yi yio tunbọ so okun ọre ilu on pẹlu Ghana po si ẹpọ ọdun s waju.

Printed & Published By The Union Printing & Publishing Company 28, Kosoko Street P.O. Box 467 Phone No 23370